# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 818 LAGOS SATURDAY MAY 5. — MAY 11, 1962. KỌBỌ MEJI (2D)

# Iyan Fe Mu Ni Ilu Eko, Gari Di Sile Marun Fun Panu Kan L'oja

Eko — Gbogbo awọn obinrin ti nwọn lọ si ọja Ebute - Ero ni owurọ ọjọ Alaruba, ( Wednesday) ọjọ kẹta oṣu yi, ni nwọn ni lati ki'gbe ibosi o! sare pada wa sile lati wa gba owo lọwọ ọkọ wọn fi kun owo ti nwọn mu lọ, nigbati nwọn gbọ wipe owo gari ti di ṣile marun (5/-) fun panu kọkan Ṣile mẹta abọ ni nwọn ta ni ọjọ Atini, (Monday).

Onirohin wa sọ fun wa wipe ogunlọgọ apo gari ni awọn ti o nṣe iṣe onjẹ-tita ti fi mọto ko kuro ni ebute Ikorodu ati ni ilu kan ti nwọn npe ni Gbogbo lẹba Ikorodu na. Ọpọlọpọ awọn ti o nta gari ni ọja Oyingbo, l'Ebute-Mẹtta, ni gbogbo apo gari ti awọn ti ra pamọ sile, ni wọn ti ra lọwọ awọn tan.

Nwọn tun ṣe alaye wipe ọdun Ileya ni o mbọ yi. awọn onigari Ikorodu ko ni ri aye ko gari wọ Eko mọ fun oṣu kan. Iyan nla ni o mbọ yi, ara Eko, e kiyes'ara.

**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY WARRI SAPELE,
ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell
Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Natbaniger ; London
Head Office Representatives in London.
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURGH

## Awon Omo Egbe Eko Parapo Tun Se Ipade

Eko— Ni ọjọ Iṣegun (Tuesday) ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Eko Parapọ (Lagos Citizens' Rights Protection Council) tun ṣe ipade pataki kan ninu ọgba-iworan Sinima ni Ita Faji l'Eko, ẹsẹ awọn enia pataki pataki lọkunrin ati lobinrin lo pe sibi ipade na.

Baba Ẹgbẹ na Oloye T. Adebayọ. Doherty ni o kọ-kọ sọrọ. O ni on kesi gbo-gbo ọmọ Eko ti nwọn mbẹ nile ati lẹhin odi, ki nwọn wa wọ ẹgbẹ na, ki nwọn fi ohun ṣọkan lati bere awọn nkan ẹtọ ti Ijọba ni lati ṣe fun awọn ara Eko ti nwọn ko si ṣe fun wọn.

Oloye Doherty ni ọkan ninu iya ti nwọn fi njẹ ara Eko na ni ọrọ ilẹ Falọmọ ti Ijọba ni awọn ara Eko ni awọn yio gbe ibẹ fun, ṣugbọn nisisiyi, o ti di ti awọn ajeji. Oloye Doherty ni Ijọba nrẹ awọn ọmọ Eko jẹ pupọ ju.

O sọ wipe nigbati nwọn nṣe eto ilu (Nigerian Constitution) ni ilu Oyinbo, eto ifinisọfa si oko ẹru ni nwọn ṣe fun awọn ara Eko. O sọ pe nigbati a wa labẹ Ijọba Oyinbo, awọn Oyinbo Ajẹlẹ ni nwọn fi ṣe alaṣẹ ilu Eko, ṣugbọn nisisiyi, abẹ Minisita kan ni nwọn fi ilu Eko si. O tun tẹsiwaju pe bi enia ba ti mọ ẹtọ rẹ, ko si nkankan ti o di lọwọ wipe ki o ma se bere nkan ti o tọ si i lọwọ Ijọba. Eyi ni on pe awọn ara Eko l'ọkunrin ati l'obinrin si wipe, ki awọn sowọpọ, ki ẹgbẹ tuntun yi bere gbogbo nkan ẹtọ ti o jẹ ti ara Eko lọwọ Ijọba.

Ẹniti o tun sọrọ ni Alhaji L.B. Augusto. O ni on faramọ gbogbo nkan ti Oloye Doherty sọ. O ni ki awọn ọmọ Eko wo bi aiye na ti nlọ si, gbogbo awọn ọmọ ilu olukuluku ni Ijọba wọn fun ni ẹbun lati k'awe lọfẹ (Scholarship) ni ilu Oyinbo, ṣugbọn anfani yi ti o wa fun ọmọ Eko, ẹnikẹni ni nwọn ngbe e fun. Alhaji Augusto ni on kesi awọn ara on ni ilu Eko, ki nwọn ṣe alatilẹhin fun ẹgbẹ tuntun na ki awọn le fi ṣe ẹgbẹ akọya.

**WANTED**
Bank Notes Of French African Territories
Offers:
B M / BLPR
BCM/MONO
LONDON W. C. I.

## Ipade Awọn Oba Ati Ijoye Ipinle Iwo-Orun

badan— Ninun ipade ọjọ meji ti awọn ọba ati Ijoye ipinlẹ Iwọ-orun bẹrẹ ni ọgbọnjọ oṣu April 1962, ni ilu Ibadan, nwọn yan awọn Igbimọ ti yio lọ ṣe aṣaro lori ọrọ awọn oye ti nwọn fi nda awọn enia l'ọla, ni ipinlẹ na. Awọn Igbimọ na yio ṣe aṣaro gẹgẹbi ẹtọ ti enia ni lati ni ki nwọn to fi oye da l'ọla.

Nigbati Oloye Ọbafẹmi Awolowọ mba nwọn sọrọ, o sọ ninu ọrọ rẹ wipe nigbati on da ipade awọn ọba ati Ijoye yi silẹ, awọn alatako tako wipe ipade awọn ọba ati Ijoye di meji, o sọ wipe irufẹ atako bayi ko dara to, ko si ni gbongbo.

Nigbati a da ipade yi silẹ ninu ọdun 1956, awọn Ọba ati Ijoye mẹrin-le-ladọta l'owa ninu ile Igbimọ l'ọba-l'ọba, o si ti goke di meji-dini-lọgọfa nisisiyi, gẹgẹbi aṣaro ti a ṣe ninn ipade ti ọdun 1958.

Ṣugbọn, pẹlu bẹ na, o ṣi ku bi irinwo awọn ọba ati Ijoye ti o jẹ pe inu ipade yi ni nwọn ti nmọ nkan ti Ijọba nṣe ati eyiti o nfẹ ṣe, ti nwọn si mba nwọn ṣe aṣaro le lori.

Gbogbo awọn ọba ati Ijoye ni nwọn ha iho-ayọ nigbati Oloye Obafẹmi sọ wipe, niwọn igbati ẹgbẹ Afẹnifẹre (Actio Group) ba wa ni Alaṣẹ ipinlẹ Iwọ-orun ipade wọn na ko duro rara, io si maa lọ deedee.



Ninu ipade awọn ọba ati Ijoye ti a nsọrọ rẹ yi, bakanna ni Oloye S. L. Akintọla, Olotu Ijọba Iwọ-orun n a ba awọn Ọba ati Ijoye ṣọrọ, o dupẹ fun wọn, gẹgẹbi nwọn ti duro ti Ijọba rẹ ti o fi ṣe aṣepe iṣẹ, o si la idi mọkanla ti Ijọba rẹ fi tako ọrọ ipinlẹ kẹrin fun wọn, ati bi nwọn ti fi ipinnu ti nwọn ṣe ranṣẹ si Ile Igbimọ meieji Iwọ-Orun ibi ti o tọ si, o si sọ wipe Ijọba on yio duro lori ipinnu rẹ jẹjẹ lati ri ohun ti nwọn yio ba ṣe.

## AWO'RAWO

Eyi ni awọn nkan ti yio ṣẹlẹ si ọ ni ọsẹ yi.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 21) Ṣọ ara rẹ pẹlu nkan ti o wu ọ ki o ma ba ko aisan ba ẹ.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Gbẹkẹle ara rẹ: Pinnu pataki wa ti wa ṣe lori ọrọ ara rẹ.

ARIES (Mar 21-April 20) ṣọ'ra pẹlu ọrọ pati-pati.

TAURUS (April 21-May 20) Maṣe jẹ ki awọn nkan bi aajowu tabi nkan bẹẹbẹ gba ọkan rẹ.

GEMINI (May 21-June 21) Awọn ukan ti o ko ti nṣe ri ni wa fẹ ma ṣe ninu ọsẹ yi.

CANCER (June 22-July 23) Ṣọ'ra pẹlu ailera ati irẹwẹsi, ki o si maṣe ẹ ki iroju ba ọpọlọpọ ohun-rere jẹ fun ọ.

LEO (July 24–Aug 22) Maṣe ṣe gberaga, gbogbo awọn nkan to ba na'wọle ninu ọsẹ yi ni a ja si rere fun ọ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Gba imọran ti nwọn ba fun ọ, ma ṣe jẹki irẹwẹsi gba ọ l'ọkan.

LIBRA (Sep 24-Oct23) Inu didu ati ara yiya a jẹ ki ọpọlọpọ awọn nkan ti o ba ṣe ninu ọsẹ yi yọri si rere.

SCORPIO (Oct 24-Nov 23) F'arabalẹ ṣe awọn nkan rẹ leto-leto ninu ọsẹ yi, ki o ma tẹ lọwọ awọn ti o fẹran rẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23–Dec 22) Bi o ṣe la'wọ to ni awọn enia yio fẹ fi iwọsi lọ ẹ ninu ọsẹ yi.

CAPRICORN (Dec 23–Jan21) Gidi-gidi-ko-mọla ni ọrọ rẹ l'ọsẹ yi.

# Ipari Ipade Eto Ilu Kenya



Ọgbẹni Ronald Ngala, ti iṣe Aṣiwaju ẹgbẹ Kenya African Democratic Union (KADU) ni a nwo ni aworan pẹlu Sir Michael Blundall yi nibi ipari ipade eto iṣelu Kenya ti nwọn ṣe ni ilu nla London laipẹ yi.

Nisisiyi, nwọn bẹrẹ si ṣe eto Ijọba Ajumọṣepọ ti nwọn fi da silẹ nilu wọn pẹlu Gomina ilu na, Sir Patrick Renison.

## Egbe Omo Ilorin Nigeria Se Ipade Ni Mushin

MUSHIN —Ni ọjọ Satide ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn ṣuo ti o koja yi ni awọn Ẹgbẹ ọmọ Ilọrin ṣe ipade alarinrin kan ni ile akapo-owo ẹgbẹ na ni Ogunmokun Street, Mushin. Ki akoko ti nwọn fi ipade na si to to, gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ na ni o ti pe sibẹ patapata.

Alufa Ashafa ni o ṣe alaga ipade na. Gbara ti ipade na ti bẹrẹ ni nwọn pe Alihaji A. O. Waliyi, oloye alakoso ẹgbẹ na pe ki o ki awọn alejo ti nwọn gba ni ọjọ na ati pe ki o si ṣe alaye gbogbo idi ti nwọn ṣe da ẹgbẹ na silẹ.

(Wo yoku loju ewe keje)

# E MA TUN SE ASISE LOTEYI O

Olotu Ijọba Iwọ-Orun, Oloye S. L. Akintọla ṣe ikilọ fun awọn enia ilẹ Ọshun nigbati o nṣe ikede ti enia kika ti Ijọba nfẹ̀ṣe fun̄wọn nilu Igbaye ni Odo-Ọtin.



Ninu ipade na, awọn enia ti o pe sibẹ to ẹgbarun (10, 000) lati gbogbo agbegbe Ọshun. Oloye Akintọla sọ wipe ki nwọn maṣe tun ṣe irufẹ aṣiṣe ti nwọn ṣe ninu ọdun 19 52, ki nwọn jẹki awọn akania ri gbogbo wọn ka ni ọjọ kẹtala oṣu May, yi.

Olotu Ijọba tun tẹ siwaju pe nipa kika enia yi n anfani pupọ wa fun awọn ilu lati mọ iye enia ti o tọ lati yan sinu igbimọ nla ati igbimọ ibilẹ ilu kọkan.

## Oro Ipinle Fe Da Ija Sile Ni Benin

BENIN CITY - Ọrọ apinlẹ n i Iwọ-orun t i fẹ bi Ige ati Adubi ni ilu Benin ati agbegbe rẹ. Ni ọjọ Satide ti o kọja lọ yi, gbogbo awọn ọmọ Urhobo (Isobo) ti o wa ni Apapa-Ajegunlẹ, Ebute-Mẹtta ati Ọbalende ṣe ipada pajawiri kan nipa ọrọ Ipinlẹ Ijọba Iwọ-orun (Mid-West) na.

( Wo yoku loju ewe karun )

# Ogun Igbonse Se Jamba

Ilesha— Ni aṣalẹ ọjọ ọsẹ tokọja ni a gbọ pe iya kan ati awọn ọmọ rẹ mẹrin ni nwọn gbe lọ si Ile Iwosan ilu Ilesha fun ogun igbọnsẹ ti nwọn mu ti o ko iyọnu ba wọn.

Ọkọ obinrin na ko si nile ni owurọ ọjọ na, nigbati iya awọn ọmọ rẹ fun awọn ọmọ na ni ogun iyagbẹ kan mu, on paapa si mu tirẹ na. Nigbati baba awọn ọmọ pada wa sile ni o wa ba gbogbo wọn ninu amodi, ko ṣopo-ṣe meji, o yara ko wọn lọ si ile Iwosan.

A gbọ wipe mẹta ti ku ninu awọn ọmọ na, iya wọn ati ọmọbinrin kan ti koiti ku wa ni ẹsẹ kan aiye ẹsẹ kan ọrun.

Ẹnyin ti o nmu ogun igbọnsẹ, e f'esọ si o.

## Obinrin Aboyun W'ewon

OWERRI - Obinrin a b i- lekọ kan ti oyun wa ninu rẹ ni a gbọ wipe o ṣa ọ k ọ rẹ l'ọbẹ lọwọ ni ọna meji, nitoripe ọkọ na mbawi wipe onjẹ t i o fun on ko dara.

Nigbati ọkọ ti ibiṣẹ rẹ d e, t i obinrin n a b u onjẹ fun u, ajẹti ni ọ k ọ fi onjẹ na ṣ e: o wa pe iyawo rẹ, o f i han wipe onjẹ yi ko se j ẹ rara. Nibẹ ni ọ r ọ t i nwọnu arawọn, ni iyawo aboyun fi yọ ọ b ẹ ti o si fi ṣa ọkọ rẹ lọwọ l'ọna meji.

Nigbati ọ r ọ n a d e iwaju Adajọ o ṣa obinrin aboyun na si konko ẹwọn oṣu mejidinlogun pẹlu iṣẹ aṣekara.

Jewelleries



Perfumes, Charms,
Amulets,
Hindu Gods in the Jewelleries




# ELETI-OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI OFẸ," LAGOS.
P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 818. SATURDAY MAY 5 - MAY 11, 1962


# Eru Jeje Mba'lu Eko

Gbolohun ti a fi ṣe akọle wosika wa ọsẹ yi jẹ ede ti o njade lẹnu ọpọlọpọ enia ni ilu Eko wa yi, ni asiko "Ọmọ-meji L'a wo silẹ" ti okiki rẹ nṣe rọnyin yika ilu wa nisisiyi.

Ewo ni koto ba enia lẹru nibẹ? nigbati nwọn ko fi mọ lori awọn ọmọde, ti o tun jẹ wipe agbalagba enia ni awọn eru'ku ti o nwa ọla ojọ na tun gbe lọ lo, lati fi ṣe iṣẹ buburu wọn, lati le ni owo tabua laiṣiṣẹ. Bi enia ba wa ninu ile rẹ, ko ni ifọkanbalẹ, bi o ṣesi ran ọmọde niṣẹ, ti o ba ṣe npẹ diẹ ki o to pada de, ominufu-ẹdọfu ni oluware yio wa.

Nitorina, a fi wosika wa yi kesi awọn olutọju alafia ilu wa wipe ki nwọn ba wa mojuto eru jẹjẹ ti o mba ilu Eko yi.

Ẹ gbawa lọwọ "Ọmọmeji Da'wolẹ"o.

---


**Plushes, Velvet, Velveteens, Damask**

**& Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

(63, Massey Street, Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.


# Iwe Si Olotu

## Minisita Olowo Ojiji

Ẹ jọwọ, ẹ gba mi laye ninu iwe nyin "Eleti-Ọfẹ" lati kin awọn oniwe irohin wa lẹhin nipa ọrọ a nko ọrọọ jọ laburadi, ti nwọn ni awọn minisita miran nṣe. Nitotọ, a mọ wipe diẹ ninu nwọn ti l'owo lọwọ ki nwọn to maa ṣe iṣẹ minisita yi, sugbọn, o yẹ ki a maa ṣe kilọkilọ fun nwọn ni ẹkokan, ki nwọn maṣe ṣi iwa hu nipa ọọrọ kikojọ.

Nwọn ni ifẹ owo ni gbongbo ẹṣẹ. Iru ọrọ ifẹ owo bayi ni o mu Dokita Nkrumah da ogunna-gbongbo kan duro lẹnu iṣẹ minita re laipẹ yi, ti o si tun gba ile olowo iyebiye ti o kọ lọwọ rẹ.

Ẹnyin Minisita onigba ojulo, ẹ ṣọra, awa ara Nigeria paapa nṣọ nyin lọwọ ati lẹsẹ.

Emi ni,

Ogbomọshọ T. Alabi.

## Owo-Ehin, Owo Abosi

Mo bẹrẹ f'oji o; ẹ ba wa kesi awọn ọga Ọlọpa ki nwọn ṣe ikilọ fun awọn ọlọpa ti o nmu owọn awa-moto ki nwọn ye gba owo-ehin (bribe) lọwọ awọn onimọto ti nwọn nlu ofin Ijọba lojojumọ.

Iwa a ngba riba yi ti dun mọ nwọn pupọ ti o fi di wipe wọn ko le fi silẹ mọ, awọn tilẹ ni awọn ọlẹ ọkunrin kan ti o mba nwọn gba a. Bi ọlọpa ba ti da onimọto kan duro, wa ri ọkan ninu ọlẹ ọkunrin na ti nwọn yio ti jade si i.

Ọpọlọpọ wọn wa ni Idumọta l'Eko ati ni Ogunpa ni Ibadan, bẹna si ni nwọn kun Ẹnugu.

Owo riba ti nwọn ngba lọwọ awọn awa-mọto yi ni o nje ki jamba moto maa pọ si i. Ẹ jọwọ, ẹ ba wa sọ fun ọga awọn ọlọpa na ki o kilọ fun nwọn o.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni.

AGEGE J. AYẸNI

---


# OKUJA WỌ'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE-FI-MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

**E Polowo Oja Nyin**

**Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**

# Ema Ka Iwe Irohin Eleti - Ofe

**Ti o kun fun Irohin Aadun Losose**

# Nihin, Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

### ỌDUN IPẸLA NI ỌDUN ILEYA

Ayiluka nki nyin o! O ni on ko ba ti mura lati lọ si irin-ajo sugbọn ọpọlọpọ ọdun ni o wa ni ile ti on ni lati ṣe. Awọn ọdun bi ọdun Ipẹla, ọdun Ogun, ọdun Ileya, ọdun Ẹ'uku ati ọdun Oro. Ọrẹ mi, ọdun ni ọdun jẹ; ko ba jẹ ọdun Imale tabi ọdun Kiriyo tabi ọdun abalaiye – iyẹn ni ọdun Ipela ti awọn Onigbagbọ sọ di Ikore ni aiye nisisiyi.

Nwọn ni:
Jorogbo, jorogbo,
Nwọn ki roju jẹ igba orogbo;
Jobi, jobi, nwọn ki roju jẹ igba obi;
J'ata, j'ata, nwọn ki roju jẹ igba ata;
Ọruumila ni aiye a roju nigba t'on.

Aiye a roju nigba t'emi ọmọ Abati atefa-tẹna, Aiye a oju fun gbogbo wa o. Ọba Odumare a jeki ọdun ti a fẹ ṣe yi ki o tu, ki o ba fun gbogbo wa o. Ṣugbọn ki a ma ji eran agbo alagbo fi fi ṣe ọdun Ileya; ki a mi ṣe ji emu ẹlẹmu gbe fi lọ bọ ogun; bẹni Oriṣa Ẹla ko ni fẹ ki a fi iṣu ti a ji gbe loko oloko bọ ipori on nitoripe:

Eke a mu pa eleke,
Ọdalẹ a si ma pa awọn ọdale.
On ni Ifa ti a da fun awọn amokun-s'ole
Ti Nwọn ni oba aiye ko ri nwọn.
Bi Ọba aiye kori nwọn
Ọba Ọrun nwo nwọn.

### OYINBO TATE

Ẹyin ọkawe mi ewo ni ẹ se si ọrọ Oyinbo ti nwọn ni ko kuro nilu ni apapandodo? Ọgbẹni Tate papapa mi ti fi ada kori ọ: ọkunrin ni. Koko, ekurọ ati epo ni nwọn nwa ni ilu Oyinbo, nwọn ko wa ẹgberun iru Tate ni ile mọ. Bi o ba lọ si ilu Ghana tabi India wa ri iru Ogbẹni Tate nibẹ.

Ki atilẹ wa tun ọrọ na yewo-kinni Ogbẹni Tate gbe ninu igba wa ni Nigeria? ko ji wa ni koko ka, ko gbe wa ni apo ekurọ, ko wipe ki tiwa ma dara. Ọmọ ti o fẹ lowọ wa ti loyun fun un; tabi ẹ ko tilẹ fẹ ki o ṣe idana fun wa ni? O ni lati san owo iya-gbọ ati baba-gbọ fun wa lori iyawo rẹ Philo.

Nwọn bi Tate paapa nibi rere; awọn iran rẹ, iṣẹ onjẹ ni nwọn nṣe, bi ki awọn maa ṣe ṣuga tabi nkan bẹẹbẹ.

### ARA MẸKA, Ẹ KU ALEJO

Irin-ajo Mẹka ọdun ni yio dun pupọ; bi awọn kan ti nlọ ni Ijọba nfi ọko ofurufu ko awọn kan ti o ti tan si ọhun, wa sile. Awọn iru enia bẹ ti Ijọba ti fi owo ara wọn ru wa ile na ju ẹgbẹrun meji lọ.

Mo gbọ wipe bi enia ba fẹ lọ si Mẹka ti ko ba fẹ tan si ọhun, ẹhin ni ki o fi jade lati inu iyara rẹ si ita; ṣugbọn ko damiloju wipe awọn Larubawa ati Hausa nṣe bẹyi. Tabi kilo fa ti nwọn fi pọ ninu awọn ti nwọn tan si ilu na? Ju gbogbo rẹ lọ, awọn ara Mẹka ni a ki nwọn ku alejo. Oja koko wọn si fun tita. Ẹ̀ala Makawia ati Tẹsuba oni igbaa-ahọn.

### OGOGORO FẸ GBAYI

Mo ri wipe ki o to to ọdun meji si igba ti a wa yi, ọti ogogoro a ti gba iyi lọwọ awọn ara Nigeria. Eyi ni ọrọ ti o ta si mi leti nibiti mo gbe ti mba awọn "burọda" mi jiroro ni Apapa-Ajegunle laipẹ yi.

Nwọn ni bi awọn ba ti gba iwe-agbara lati ya kuro lọwọ awọn baba-amusin awọn ni Iwọ-orun Nigeria, awọn a fi iṣẹ rọba (rubber) ṣe owo, ṣugbọn ninu iṣẹ ọti ogogoro ni awọn yio ti maa ṣe ọla ati ọla.

Ọrọ re o, Omimi Ejo! Boya o ko mọ bi ọrọ ti nlọ si ni Warri ati Sapẹle, ṣugbọn emi Ayiluka ni ti o ba de Burutu, Isoko ati Forcadosi, wa ri wipe, ọpọlọpọ ile agbẹmu-yọna ni a ti fẹ pari tan fun ayọ a-pinlẹ-a-ko-pilẹ Iwọ-orun ti mbọ laipẹ yi, ṣugbọn awọn ọmọ Itsẹkiri ati Ọba wọn, Olu, ni awọn ko ṣe ẹgbẹ afaṣọya.

# Iranse Fun Ọba Obinrin Ni Ghana



CHANA - Ọmọ ile Ghana, Major Michael Otu ti a nwo aworan rẹ ti o fi agborun bori nigbati o jade ni Afin Ọba ilu Oyinbo yi ni o ṣe iranṣe fun Alaiyeluwa Elizabeth Keji, Ọba obinrin Oyinbo ni asiko Abẹwo rẹ ni oṣu November ti o koja yi.

# Oro Ipinle Fe Da Ija Sile Ni Benin

(Ọgbẹrẹ loju ewe kẹta)

Awọn ara Benin ti dasi meji nisisiyi nipa ọrọ na; awọn kan Edo, awọn kan Benin. Awọn Edo ni awọn ko fẹ ki awọn kan tun ma rẹ awọn jẹ bi gbogbo ọrọ Ipinlẹ na ba ti yọri si rere; nwọ ni eyiti awọn sin idile Yoruba to, nitoripe iran Ọba Benin paapa, iran Yoruba ni.

Awọn Urhobo sọ wipe, ilu Warri ni awọn fe ki nwọn fi ṣe olori (head-quarters) awọn ko fẹ ni ilu Benin tabi Asaba. Nitorina ni awọn ṣe tun ebute ọkọ ṣe daradara ni ilu Warri na.

Onirohin wa ni on gbọ wipe awọn ara Asaba ni Ogbẹni Dennis Osadebe ni awọn fẹ fun ni oye Gomina ipinlẹ tuntun na.

Ju gbogbo rẹ lọ, awọn Ijọba mba iṣẹ wọn lọ lori ọrọ ipinlẹ tuntun na.

# E Fa Okan Nyin Ya, Ki Ise Aso Nyin

(Lati owo J. Ola. Wins)

Mo fi ọrọ mi oke yi ki gbogbo ẹnyin Onigbagbọ pe ẹ ku ọdun Ajinde, ajinde ara yio ma je o amin. A tun k gbogbo ẹnyin ọmọ iya wa yoku lai da ẹnikan si.

Jesu ni ki a fa ọkan wa ya, ki ise aṣọ wa. Eyi jẹ ọrọ pataki fun enyin onigbagbọ lati tẹle, o yẹ ki iwa ati ise nyin ba ti Krist ti ẹ nsin mu, ẹ tun ọkan nyin ṣe, ẹ ni iyọ'nu.

Nitoto, gbogbo ẹ n y i n onigbagbo t'ọ m ọ d e ati agbalagba ni ẹ bere si ma bu Ọgbẹ ti Judasi Isikariọti pe o gba owo lọwọ awọn agba-gba Ju lati ta ẹjẹ alaiṣẹ silẹ. on ni o fi Jesu han ti opọlọpọ iya fi jẹ ẹ.

Loni nkọ? Ki ni e nṣe? Iwa ti nyin na buru ju ti Judasi lọ. o yẹ ki ẹ ro inu nyin wo daradara. ẹnyin ni ẹ nda aiye ru, ọti mimu ti ọrọ Ọlọrun lodi si, yiyi ọrọ Ọlọrun po, owo-ẹhin tabi riba, ọwọ ẹnyin onigbagbọ lo pin si. Jesu ni ẹ fẹran ọta nyin, ẹ gbadura fun awọn ti nfi nyin bu—lo ni nkọ? Ṣe ẹ nfi buburu san buburu ti ẹ nfi ire san ire, eyi ti Ọlọrun lodi si.

Jesu ni fẹran ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ. sugbọn ẹnyin ni fẹran ara rẹ, si korira ọmọnikeji rẹ. Ẹ fa i w a buburu ọkan nyin ya, ẹ ma tun kan Jesu mọ'gi mọ nipa iwa ti ẹ nhu. Jesu ni ni iyọ aiye, anu ṣe mi lati sọ wipe iyọ nyin ti di obu.

Laiye atijọ, onigbagbọ ni a mọ ni enia rere, sugbọn ẹ ti ba iwa na jẹ, laiye atijọ Josefu ki pa irọ, Samuẹli ki igbe ọmọ ta. Nitorina, a iko wa lati tun iwa wa ṣe, ki a maa tẹle ẹkọ Jesu Krist Oluwa wa Ki ẹni ti njale fi ole jija silẹ. ẹni ti npa'rọ fi irọ pipa silẹ, ti awọn iwa ti ko ba ẹkọ Bibeli mu.

Eyi ti o wa buru julọ na lati ri wipe, o n i g b a g b ọ ngba riba. Ah! eyi ma kamimi o, ẹni ti nwa i ṣ ẹ onjẹ ọjọ ti a ni ki o lọ mu owo wa (ṣe chun ti a mọ ni wipe ako mọ, ẹni ti oya owo lọdọ enia mẹwa ati mọ wipe ko ni owo lọwọ) oyẹ ki a ni anu ara wa, nitoripe anu ni a fi da wasi, osi tun pọ ninu awọn onigbagbọ ti ki si san owo ọya fun awọn oṣiṣẹ rẹ. iyẹn na ko ba oun Ọlọrun mu. Bibeli ni maṣe jẹki o- ... gbẹ ki o t ... un owo fun.

Ẹ jọwọ, alaye ni a nṣe fun ara wa, mo nran nyin leti ọrọ Mimọ Ọlọrun ni.

TANI GBE IYAWO TANI NKO ERUPE"?

Mo fi iyọnu Ọlọrun bẹ ẹnyin ọdọmọde, paapa ni ilu Eko, ki a yago f u n iwa jagidi-jagan j ẹ j ẹ ni awọn onigbagbọ nṣe ọdun Ajinde wọn, e wo wa ni ti egungun ti njade? o to akoko fun wa lati mu- ra fun idagbasoke ilu wa, mo gbagbọ wipe a w ọ n onigbagbọ ki iṣe egungun rara, nwọn bọ lọwọ Oriṣa, kini ero ti nyin ti ẹ mba ọdun ọlọdun jẹ, mo tun bẹ nyin dada ẹ ṣọ ara nyin.

Awọn odi-keji wa, Imale tabi Musulumi sọ wipe, ki Ọlọrun p'ana keferi (nwọn ni ki awọn ẹranko ma a wa gbadun aile larin enia, asin fo kọkọ de, nwọn fi ṣe ogun ipara, njẹ awọn yoku yio wa mọ? sugbọn Rabiu Musa, ni otun ngbe egungun, eyi ha dara bi?

Mo mbẹ ẹnyin Musulumi ki ẹ kilọ fun awọn to mba orukọ nyin jẹ, nitoripe Imale ki jọ bata, nibo ni awọn enia wọnyi ti gba ẹsin Ọlọrun pelu ibọriṣa pọ? Jesu sọ fun wa wipe, iranṣẹ kan ko le sin ọga meji pọ ni ẹkanna. Nitorina, a kole sin Ọlọrun pelu mamoni, a ko le sin Ọlọrun ati Oriṣa pọ bi o ba fẹ ṣe egungun, ki o pa orukọ enia mimọ ti, ki o ma jẹ orukọ oriṣa a t i egungun.

Oju ko fẹra ku o.


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.


## ELETI-OFE D'ARABA

## New London Rail Terminal For West African Passengers

LONDON—Travellers by air to and from West Africa will, as from this month be able to use the new terminal built by British United Airways at Victoria Station, at a cost of £100,000.

The terminal is being formally inaugurated recently, barely six months from the date on which the work of construction was begun.

The steel and glass terminal, 13,400 square feet in area, is built on a concrete "raft" raised fifteen feet above above the main station level on reinforced concrete stilts. Passengers will ascend by escalator to the concourse where they will be checked in for their flights. When their flights are called they will go on to a footbridge which spans the seven platforms from which trains run directly to Gatwick Airport with its own built - in railway station.

The new terminal thus completes the world's first rail-air link with a main line railway station. It will be used by passengers on British United scheduled services to Central, East and West Africa as well as those flying on the airline's other worldwide routes.

## British Company Launches Nigeria Scholarship Scheme

London—The first Nigerian to receive a De La Rue scholarship- offered by the famous British bank-note printing firm of Thomas De La Rue and Company, to mark Nigeria's independencehas arrived in Britain to start a hree-year course of study in typography.

He is Mr Alilu Babatunde Badmos of the Federal Ministry of Information printing office, Lagos, who hopes to return to Nigeria as a qualified typographical designer in three year's time.

The scholarship is part of a ten-year scheme to enable suitably qualified Nigerian men and women to study printnig in Britain.

"The aim of the scholarship is to help strenghten the art of printing in Nigeria", a spokesman for the company told our correspondent at the weekend.

"The scholar is chosen by the Nigerian Goverment, and the scholarship covers his fares to and from Nigeria and his tuition fees, books, accommodation and living expenses while he is studying here".

Mr. Badmos has now started his studies at the Camberwell School of Arts and Crafts in London.

# Ipade Eto Ilu Kenya F'enusokan



Ọgbẹni Jọmọ Kenyatta, ti iṣe Alakoso ẹgbẹ oṣelu ti nwọn npe ni (KANU) Kenya African National Union

ni a nwo ninu aworan yi ti o mba awọn aṣoju sọrọ nibi ipari eto iṣelu wọn nilu Oyinbo laipẹ yi.

Lẹhin ipade aṣaro fun oṣu meji ni awọn ẹgbẹ mejeji f'ohun ṣọkan pọ larin arawọn lori eto iṣelu ti Ọgbẹni Reginald Maudling ṣe fun wọn. Ẹgbẹ KANU ati Ẹgbẹ KADU, ti Ọgbẹni Ronald Ngala nṣe aṣiwaju wọn.

## Egbe Omo Ilorin Nigeria Se Ipade Ni Mushin

(C bẹrẹ l'oju ewe keji)

Nwọn ni awọn da silẹ fun lati ma ran gbogbo ọmọ Ilọrin lọwọ ati fun idagbasoke ilu na jake jado. Nwọn ni ẹgbẹ na ki i ṣe ẹgbẹ oṣelu; awọn ko si nda ọrọ oṣelu (politic) sile ni:oripe ẹgbẹ na wa fun gbogbogboo ọmọ Ilọrin l'ọkunrin ati l'obinrin. Ara Oro, Ajasẹpo, Ọffa, Oke-Ọdẹ, Omupo, Igbaja, Sharẹ ati gbogbo ọmọ ilu ti o wa labẹ Ilọrin ni nwọn le wọ ẹgbẹ na.

Nwọn tun ṣe alaye wipe awọn ti mura tan lati da ẹka ẹgbẹ na silẹ kakiri ilẹ Nigeria; awọn si fẹ da iṣẹ-ọwọ silẹ fun awọn ọmọ Ilọrin ti ko ri iṣẹ ṣe. Nwọn ni awọn na ti ri bi awọn ẹgbẹ ọlaju miran ti nṣẹ ran awọn ọmọ ilu miran lọwọ.

Lẹhin eyi Alufa A. R. B. Akewuṣola, tiṣe Olove Ayẹwe owo-wo ẹgbẹ na ati Alihaji A. W. I. Anifywoṣhe, akọwe ẹgbẹ na sọrọ iyanju.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Ilori Je Oye Are Gbogbo Egba L'Abeokuta

ABẸOKUTA—Awọn enia pataki-pataki lati Ipinlẹ Iwọ—Orun wa, ni Orile Ijaiye, Ibadan ati l'Eko ni nwọn wa sibi aseyẹ ifinijoye ti nwọn ṣe ni Afin Ake, nigbati nwọn fi Victor Adedọlapọ Ilọri, Ọga—Agba awọn adajọ-ibilẹ je oye Arẹ gbogbo ilu Ẹgba. Ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ Ijaiye l'ọkunrin l'obinrin lo pe sibẹ nitoripe Balogun Ijaiye ni Oloye Ilọri ti jẹ tẹlẹ.

Nigbati ojọ oye na ti ku ọla ni Oloye na ti şi ile tuntun ti o kọ si adugbo ti nwọn npe ni Adaatan ti o si fi nkan jijẹ ati mimu te ogunlọgọ awọn enia ti o wa sibẹ l'ọrun. Eto ifinijoye paapa bẹrẹ lowurọ ọjọ ọsẹ to kọja ni agogo mọkanla.

Ki awọn to ja ewe oye le Oloye Ilọri na lori, Alaiyeluwa Ọba Ademọla sọ ọrọ iwuri diẹ ninu eyiti o mu ẹnu kan iwa rere ti baba Oloye na ma nhu nigba aiye rẹ. Ni ipari ọrọ rẹ, Ọba na ni, on kan saara si gbogbo Ẹgba ati awọn ọmọ Ijaiye fun ifẹnuṣọkan ti nwọn fẹnu ṣ'ọkan lori oye na.

Lẹhin eyi Oloye na pẹlu Alhaji D. S. Adegbenro Minisita Alakoso Ijọba ibilẹ ti tun ṣe Oloye Ẹkẹrin gbogbo Ẹgba ba gun ẹṣin ti nwọn njo, ti nwọn si nlọ leto-leto pẹlu awọn onilu.

Ni irọlẹ ọjọ na ni gbogbo awọn ọmọ Ijaiye ti nwọn ti da aṣọ ẹgbẹjọda, ti nwọn si ti fi ile pọn ọti, ti nwọn ti fi ọr.a ro ọka wa tẹfada si ọja Atodẹ ni Ijaiye nibiti nwọn gbe ṣe aṣeyẹ ẹtata fun Oloye na, ti nwọn nkọrin "Ofofo alejo, bẹ lati nṣe ara wa" ti tọmọde tagba wọn njo ijo bi awọn baba wọn ti ma njo niwaju Arẹ-Ọna Kakanfo ni Orile Ijaiye laiye atijọ. Nibẹ ni nwọn ti ka iwe-ẹyẹ ti nwọn fi si inu jigi, ti nwọn fi ki ku orire fun un.

Ninu awọn enia pataki ti o wa sibi aṣeyẹ na ni awọn Minisita Ipinlẹ Iwọ-Orun awọn Ijoye ati awọn gbajumọ ati sanmọri ilu, awọn bi Ọba Olowu, Ọba Ọshilẹ, Agura, Olubara, Ọba Aladesanmi, Ewi Ado Ekiti, Adajọ L. O. Fadipẹ, Adajọ D. O. Oguntoye, S. O. Ighedaro, Minisita alamojuto awọn nkan ti o jẹ mọ ile ẹjọ.

## Egbe Omo Ilorin Nigeria Se Ipade Ni Mushin

( O bẹrẹ loju ewe keje )

Diẹ ti aye wa lati darukọ ninu awọn Oloye ẹgbẹ na ti nwọn wa si ibi ipade ọjọ na ni Alufa Ajapẹ, Baba ẹgbẹ; Alufa Sambo, Majẹkobaje; Abudu Gafari, Balogun; Salawu Eruda, Arẹ Kakanfo Alufa Fọlọrunṣọ, Sambo, Alafin; Akande, Ọtun Alafin, Alufa Jimọ Bakare akapo owo, Ismanu, Igbakeji akapo ati A.K. Bello akọwe owo.

Ọlọrun ki o muẹsẹ ẹgbẹ na duro-Amin.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; Ololu L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.

## Omo Odun Mewa Gb'aje Eyi Ara!

AKURẸ — Awọn Ọlọpa illu Akurẹ nwa awọn enia tabi obi ọmọ obinrin kan ti o to bi ọmọ ọdun mẹwa, ti o mu ki ọja ilu Akurẹ daru nigbati o nki'gbe wipe on ti wọ ẹgbẹ Ajẹ ati pe on lọwọ ninu iku awọn arabinrin ati arakunrin on ti nwọn ti ku.

Burẹdi ni ọmọ na nkiri nigbati o nṣe bi ẹniti nkan kọlu, ti o si bẹrẹ si jẹwọ awọn ẹṣẹ rẹ. Ọmọbinrin na pe orukọ ara rẹ ni Christiana, nwọn si mulọ si mulọ si ile Ọba ki nwọn to fa le ọlọpa lọwọ.

# Ayara Bi Asa



Omidan Daphne Arden ọmọ ilu Gẹsi ti a nwo aworan rẹ yi, ni o bori ninu ere ije ti nwọn ṣe ni nilu Oyinbo Gẹsi laipẹ yi, ọmọbinrin, Omidan R. Bronnsack ti ilu Germany ni o gba ipo keji